# Ìlò Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé Fún Ìpolongo Òògùn Ìbílẹ̀ Yorùbá

**Àránsí Ayọ̀ọ̀lá Ọládùúnkẹ́,** ***Ph.D.***
*Department of Linguistics and African Languages*
*Kwara State University, Malete*
*ayoaransi@gmail.com*

## Àṣamọ̀

*Ohun tó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí ni síṣe àfihàn ọ̀nà tí àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ ń gbà láti ṣe ìpolongo ara wọn pẹ̀lú òògùn tí wọ́n ṣe fún àwọn ènìyàn nínú àwùjọ fún ìmúláradá, ìtọ́jú àti ìdènà àrùn. A ṣe àfihàn ìlànà ìpolówó òògùn láyé àtijọ́ àti òde-òní èyí tó fún wa láyè láti jẹ́ kí a mọ ìyàtọ̀ àti ìjọra tó wà nínú méjèèjì. A wo ìlànà tí wọ́n gbà ṣe ìkọ̀ọ̀kan wọn láti baà lè fi hàn pé bí ìlànà ìgbàlódé ṣe dára tó náà ni àbùkù ṣe wà níbẹ̀.*

*Ọ̀nà tí a gbà ṣe ìwádìí ni pé, a fi ọ̀rọ̀ wá àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ tí a yàn láàyò pẹ̀lú àwọn alárenà ètò ìpàtẹ òògùn ní ilé-iṣẹ́ rédíò àti tẹlifísàn lẹ́nu wò. A ṣe ìwádìí nípa iṣẹ́ òògùn wọn, bátànì tí wọn ń lò láti tajà wọn, ibi tí wọ́n tí ń ṣe òògùn wọn àti ibi tí a ti lè rí wọn rà. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí a mọ̀ pé ìlò ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ń polongo iṣẹ́ ìṣègùn àwọn Yorùbá fún àwọn tí kì í ṣe ọmọ Yorùbá. Ó tún jẹ́ kí a mọ̀ pé òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá tayọ àwùjọ Yorùbá nítorí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn tí kì í ṣe ọmọ Yorùbá ló ní àǹfààní láti gbọ́ ìpolówó òògùn wọn. Síwájú sí i, ìlò ibánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé tún jẹ́ kí òògùn Yorùbá jẹ́ ìlú mọ̀-ọ́n-ká. Yàtọ̀ sí èyí, ó jẹ́ kí á mọ̀ pé àwọn òògùn ẹ̀yà mìíràn tún ń jẹyọ nínú ọgbọ́n ìṣègùn ẹ̀yà Yorùbá. Ìpolówó òògùn lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé jẹ́ kí òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá gbòòrò sí i, èyí sì jẹ́ orísun ìdàgbàsókè iṣẹ́ abínibí ìran Yorùbá.*

**Kókó Ọ̀rọ̀:** Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀, Òògùn Ìbílẹ̀, Ìpolongo, Yorùbá

## Ìfáárà

Ìṣègùn jẹ́ iṣẹ́ kan pàtàkì tí a rí nínú iṣẹ́ abínibí ìran Yorùbá. Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá, ìlò ewé àti egbò igi jẹ́ ohun tí ó ti wà láti ìgbà pípẹ́. Àwọn Yorùbá gbà pé ìlera loògùn ọrọ̀, ẹ̀dá tó bá ní àlàáfíà ohun gbogbo ló ní. Bí ọ̀kan-ò-jọ̀kan àwọn òògùn ti wà fún iṣẹ́ ìwòsàn náà ni àwọn mìíràn wà fún ìdènà onírúurú àìsàn. Àwọn òògùn ìbílẹ̀ yìí máa ń wáyé nípa àṣàjọ ewéko, gbòǹgbò igi àti èèpo igi, yálà tí a gún papọ̀, tí a jó níná, tàbí tí a gbo fún ìlò ọmọ ènìyàn.

Ní ilẹ̀ Adúláwọ̀, iṣẹ́ òògùn ìbílẹ̀ ti di gbajúgbajà nítorí pé ejò ti wọ́ kúrò níbi tàná. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn onímọ̀ kan gbà pé òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá kò ní ètò tó gún régé, síbẹ̀ ọ̀pọ̀ nínú àwọn ènìyàn Orílẹ̀-èdè Adúláwọ̀, nínú èyí tí Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà jẹ́ ọ̀kan, ní àwọn ìgbìmọ̀ tí ń ṣe ìwádìí lórí ewé àti egbò. Ìgbìyànjú yìí fi hàn pé òògùn tí kò bá jẹ́ ewé rẹ̀ ló ku ọ̀kan. Ọpọ́n òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá tí sún síwájú nípa síṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ lóòrèkóòrè àti ṣíṣe ìpolongo ara wọn, iṣẹ́ àti ìṣègùn wọn lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé. Nípasẹ̀ ìpolongo, ọ̀pọ̀ wọn ti di gbajúmọ̀ àti ìlú mọ̀-ọ́n-ká ní ibi gbogbo tí ìpolówó òògùn bá tí ń wáyé.

Irúfẹ́ ọ̀nà ìgbàlódé yìí fún àwọn olóògùn ìbílẹ̀ ní àǹfààní láti ni àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ẹ̀yà mìíràn láti fi ọgbọ́n ran ọgbọ́n. Fífi ọgbọ́n kún ọgbọ́n yìí ṣe okùnfà kí òògùn àwọn ẹ̀yà wọ̀nyí wọnú ara wọn, èyí sì jẹ́ kí òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá gbòòrò kọjá ibi tí ó wà ní ìpìlẹ̀. Àmọ́, bí ìlò ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ṣe àfihàn àti ìgbélárugẹ àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ kíkún náà ni a rí ọ̀pọ̀ àwọn oníṣègùn mìíràn tí wọ́n jẹ́ 'awówùmí' tàbí 'awóyọjúràn', èyí tí a lè pè ní olùpàtẹ ìṣègùn lásán. Nínú iṣẹ́

yìí, rédíò àti tẹlifísàn nìkan ni ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé tí a ó ṣàmúlò. Níbẹ̀ ni a ó ti wo àwòjinlẹ̀ ọ̀nà tí àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí ń gbà ṣe ìpolongo ara wọn àti iṣẹ́ wọn lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé, a ó tún wo ìlànà ìpolówó wọn láyé ọjọ́un àti òde-òní. A wo ìjọra pẹ̀lú ìyàtọ̀ òun àǹfààní àti ewu tó rọ̀ mọ́ ìpolongo òògùn ìbílẹ̀ lorí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé.

**Iṣẹ́ tó wà nílẹ̀ lórí òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá**

Oríṣìíríṣìí àwọn onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí tewé-tegbò ìbílẹ̀ Yorùbá. Lára àwọn onímọ̀ wọ̀nyí ni Dọ̀pámú (1979: 47) tí ó ṣàlàyé pé òògùn jẹ mọ́ ewé pẹ̀lú egbòogi tí ó jẹ́ èròjà ìwòsàn àìsàn tí kò nílò agbárakágbára kan láti mú kí ó siṣẹ́ bí ó ti tọ́ àti bí ó ṣe yẹ. Ó sọ ọ́ di mímọ̀ pé òògùn jẹ́ iṣẹ́-ọnà tí à ń ṣe àmúlò láti dènà àìsàn àti láti fi wo àìsàn.

Akpata (1979: 15) rí àwọn ọdẹ gẹ́gẹ́ bí ẹni tó ní ìmọ̀ kíkún nípa òògùn. Ó sọ ọ́ di mímọ̀ pé, ìrírí ọdẹ máa ń wáyé nígbà tí wọ́n bá yin ẹranko ní ìbọn tí ẹranko náà sì jẹ àwọn ewé kan tí irúfẹ́ ẹranko bẹ́ẹ̀ kò sí kú. Irú ewéko bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọdẹ gbà pé ó lè wo ojú ọgbẹ́ tàbí ojú egbò san. Ó tún gbà pé tí ẹranko tí à ń sìn lábúlé bá ń ṣe àìsàn tí ó sì jẹ ewéko kan tí ara rẹ̀ sì dá tàbí tí ó jẹ́ ewéko kan tí ó sì kú, irúfẹ́ ewéko tó jẹ́ tó fi kú yìí ni àwọn ọdẹ yóò rí bí májèlé. Èyí tó mú un lára dá ni wọ́n gbà pé yóò wúlò fún ìwòsàn ìmúláradá ọmọ ènìyàn.

Ọ̀nà àkọ́kọ́ láti ní ìmọ̀ òògùn gẹ́gẹ́bí àlàyé Awólàlú (1979) ni kí Àjà gbé ènìyàn lọ sínú igbó kìjikìji fún bí ọdún kan sí ọdún méje nígbà tí olúwarẹ̀ yóò bá fi dé, yóò ti di olóògùn tí ó gbójú. Ó gbà pé ọ̀nà kejì ni síṣe àkíyèsí ìhùwàsí tàbí dídán àwọn nǹkan bí ewéko àti ẹranko wò. Ìkẹta ni lílo ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì lati fi

ṣàyẹ̀wò àyọrísí àwọn ewéko tí àwọn ohun ọ̀sìn bá jẹ. Ìkẹrin ni kí àwọn ọdẹ tí ó lọ ṣọdẹ nínú igbó ṣe àkíyèsí ewéko tàbí egbòogi tí àgbọ̀nrín tí wọ́n ta níbọn jẹ tí ó sì wo ojú ọgbẹ́ ti ìbọn tí bà á sàn. Eégúnyọmí (2007: 19) gbà pé iṣẹ́ idán àti ìṣègùn dúró lórí ìgbàgbọ́ Yorùbá pé àwọn agbára kan wà tí ènìyàn lè gbà láti fi jẹ́ kí èròǹgbà ṣẹ.

Olóròdé (1985: 15) ní tirẹ̀ gbà pé ọ̀nà yòówù tí Yorùbá bá gbà láti fi ní ìmọ̀ nípa òògùn síṣe, ó dájú pé wọ́n dá onírúurú egbò igi tí wọn máa ń ṣe àmúlò fún òògùn mọ̀, pàápàá jù lọ lásìkò ọ̀làjú yìí. Ó tún gbà pé ìṣègùn jẹ́ ẹ̀ka ìmọ̀ tó ní í ṣe pẹ̀lú ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì tó sì ń mu kí àṣà gbòòrò sí i nípa lílẹ orúkọ mọ́ àwọn igi yìí fún ìdámọ̀. Irúfẹ́ ìdámọ̀ àwọn ewé àti egbò igi yìí fi hàn pé oníṣègùn ìbílẹ̀ Yorùbá tàbí àwọn tí wọn ń tà á dá oríṣìíríṣìí àwọn egbò igi yìí mọ̀ yálà nígbà tí wọ́n bá ń ṣe àtòjọ wọn tàbí lẹ́yìn tí wọ́n ti ṣe wọ́n lọ́jọ̀. Agbájé (1989: 301) gbà pé ìmọ̀ tó gùn tí kò lópin ni à ń pè ní òògùn. Ó tún gbà pé ìlànà márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni a ń gbà tọ́jú àìsàn. Àwọn ọ̀nà náà ni; ọfọ̀ pípè, àgbo wíwẹ̀, àgunmu mímu, gbẹ́rẹ́ sínsín, ẹ̀pa títọ̀lá tàbí fún ìpara.

Pẹ̀lú àlàyé àwọn onímọ̀ òkè wọ̀nyí, ó dájú pé láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ní ìmọ̀ nípa òògùn ti wà. Ìlànà ìṣègùn ìbílẹ̀ jẹ́ àtọwọ́dọ́wọ́ nínú èyí tí àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí ń ṣe àmúlò ewé àti egbò igi fún ìdènà àìsàn àti ìwòsàn ara. Nínú àlàyé wọn, bí ìmọ̀ òògùn ṣíṣe ṣe jẹ́ àtọwọ́dọ́wọ́ láàrin àwọn ènìyàn bẹ́ẹ̀ náà ló tún wà láti ọ̀dọ̀ ẹranko sí àwọn ènìyàn nípa síṣe àkíyèsí àwọn ẹranko wọ̀nyí.

**Tíọ̀rì Ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-Láwùjọ wò**

Ọ̀kan pàtàkì lára àwọn tíọ̀rì tí a fi ń ṣe àtúpalẹ̀ iṣẹ́ ni tíọ̀rì ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-láwùjọ wò í ṣe. Tíọ̀rì yìí jẹ mọ́ ìbágbépọ̀ ẹ̀dá èyí tó ní í ṣe pẹ̀lú gbogbo ohun tó bá ń ṣẹlẹ̀ nínú àwùjọ. Àwọn lámèétọ́ tó ṣiṣẹ́ lórí tíọ̀rì ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbépọ̀-láwùjọ wò pín sí méjì. Lára àwọn lámèétọ́ àkọ́kọ́ tó ṣiṣẹ́ lórí tíọ̀rì yìí ni Laurenson àti Swingewood (1972: 58) tí wọ́n tọ́ka sí i pé Louis de Bonald (1754-1840) ní agbátẹrù ìmọ̀ yìí. Àwọn ọ̀wọ́ àkọ́kọ́ yìí ń wá òjìji àwùjọ nínú díńgí lítíréṣọ̀. Ìyẹn ni àwọn tó ń wá bí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ tí ń farahàn nínú lítíréṣọ̀. Lowenthal (1957) náà ṣe àfikún tirẹ̀ pé ohun tó jẹ àwọn wọ̀nyí lógún ni ipa tí àwùjọ gan-an fúnra rẹ̀ ní lórí ìgbéjáde lítíréṣọ̀ rẹ̀. Wọ́n tún ṣe àlàyé pé àwọn lámèétọ́ gbọ́dọ̀ ṣe àfihàn àwọn ìjọra ní onírúurú àwùjọ àti ìdí pàtàkì tí wọ́n fi jọra. Wọ́n tẹ̀ síwájú nípa àlàyé wọn pé ohun tí ó yẹ kí lámèétọ́ mójú tó ni ìtumọ̀ àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí. Èyí ni àwọn onímọ̀ tíọ̀rì yìí pè ní "mirror image approach". Ìyẹn ni a lè rí bí i àfidíńgí wo àwòrán tàbí ìlànà ìsínjẹ. Lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ ni àwọn tó dábàá yìí ní lọ́kàn àmọ́ ó tún wúlò fún lítíréṣọ̀ alohùn bákan náà.

Lára àwọn lámèétọ́ ìsọ̀rí kejì ni Escarpit (1971). Àwọn ìsọ̀rí lámèétọ́ ọ̀wọ́ kejì yìí gbà pé ìgbéjáde lítíréṣọ̀ àti irú àwọn ènìyàn tó jẹ́ olùgbọ́ lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀ ló yẹ kó jẹ lámèétọ́ lógún. Ohun tí àwọn lámèétọ́ abala yìí ń tẹnu mọ́ ni pé ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ló máa ń hàn nínú lítíréṣọ̀. Ìyẹn ní kí a rí lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun tó yẹ kó ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwùjọ àti òǹgbọ́. Síbẹ̀ ohun tó jẹ Escarpit lógún jù ni ìgbéjádé lítíréṣọ̀ àti bí yóò ti di rárà àti lílò.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí (1979: 47) rí tíọ̀rì ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-láwùjọ bí ẹ̀ka ìmọ̀ tó ń ṣàyẹ̀wò àjọṣepọ̀ tó ń bẹ láàrin lítíréṣọ̀, ipò wọn láwùjo, irúfẹ́ olùgbọ́, ìlànà ìṣeré pẹ̀lú ipò òǹkọ̀wé àti

òǹkàwé. Àwọn lámèètọ́ ìsọ̀rí yìí ní àyẹ̀wò lítíréṣọ̀ nìkan kò tó, ó yẹ kí lámèètọ́ rí lítíréṣọ̀, pàápàá ìwé lítíréṣọ̀, bí òwò nítorí ó lójú ẹni tó nímọ̀ okòwò ṣíṣe. Wọ́n gbà pé ó lójú ọjà tí a ti lè ṣòwò, ó lójú ẹni tó le ná ọjà ọ̀hún, ó sì tún lójú ẹni tó lè rà á. Wọ́n gbà pé ìpele tí ọjà máa ń ní nínú àwùjọ náà ni lítíréṣọ̀ náà ni. Lítíréṣọ̀ ní ọjà, òǹkọ̀wé tàbí apohùn, bákan náà ni ó tún ni òǹrajà tí a mọ̀ sí òǹkàwé tàbí òǹwòran. Wọ́n jẹ́ kó di mímọ̀ pé lámèètọ́ gbọ́dọ̀ mú ọ̀rọ̀ ìwé títẹ̀ ní kókó, àgbéjáde ìwé lítíréṣọ̀, ojúṣe òǹkọ̀wé, atẹ̀wétà tàbí olótùú nínú àwùjọ àti òǹkàwé pẹ̀lú.

Bí a bá wo èrò àwọn onímọ̀ yìí, a ó ri wí pé a kò lè ya iṣẹ́ lítíréṣọ̀ àti àwùjọ sọ́tọ̀ rárá. Lítíréṣọ̀ ni a lè rí bí èso àwùjọ, òun kan náà ló sì dàbí díńgí láti wó ìṣẹ̀lẹ̀ tó ń lọ ní àwùjọ.

Ṣíṣe àmúlò tíọ́rì yìí láti ṣe àtúpalẹ̀ òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá, èyí tí a rí bí ìlànà ìpohùn gẹ́gẹ́ bí àwọn lámèètọ́ ìsọ̀rí yìí ti sọ, ó di dandan kí lámèètọ́ wo báwo ni tíọ́rì yìí ti fara hàn nínú iṣẹ́ yìí àti onírúurú ọ̀nà tí ó gbà siṣẹ́ nínú ìpolongo òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá.

## Ẹ̀rọ Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé

Ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé jẹ́ ọ̀nà tí a ń gbà láti fi èrò ọkàn wa hàn sí ẹlòmíràn yálà olùgbọ́ wà nítòsí tàbí ọ̀nà jíjìn. Láìsi ìmọ̀ ẹ̀rọ, kò lè sí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé. Èṣo ìmọ̀ ẹ̀rọ ni ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé jẹ́. Àṣà àjòjì tó wọnú àṣà abínibí ni ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé. Ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé jẹ́ ohun tí a kà kún pàtàkì, tó ń bá wa sùn, bá wa jí. Ó sì tún jẹ́ ọ̀nà tó ṣe kókó láti jíṣẹ́ tàbí bánisọ̀rọ̀ káàkiri àgbáyé. Ẹ̀rọ ayélujára tí a mọ̀ sí ọ̀nà ìbanisọ̀rọ̀ ìgbàlódé jẹ́ orísun ìpolongo tó yá kánkán èyí tó jẹ́ ọmọbíbí inú kọ̀ǹpútà láti jíṣẹ́ fún tonílé-tàlejò lórí ohun tí a fẹ́ kí wọ́n ní ìmọ̀ kíkún nípa rẹ̀ láìsí ìfifalẹ̀ kankan rárá. Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé

yìí ní í ṣe pẹ̀lú rédíò, tẹlifísàn, ìwé ìròyìn, wásaàpù (WhatsApp), fesibúùkù (Facebook), yútuùbù (Youtube), tíwítà (Twitter), gúgù (Google), yàwúù-mésénjà (Yahoo messenger), ínsítágírààmù (Instgram), tùgóò (2go), Bàdóò (Baddo), èsìkímì (Eskimi), àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn nǹkan wọ̀nyí jẹ́ okùnfà àǹfààní láti ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ẹ̀yà mìíràn àti àwọn alábàágbépọ̀ tó wà káàkiri àyíká wa. Èyí sì ń fa ìfọgbọ́n-ran-ọgbọ́n yálà nípa àṣà àti ìṣe, ohun àjọni àti àwọn èrò kóówá wa.

Onímọ̀ kan tilẹ̀ gbà pé ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ni a lè rí gẹ́gẹ́ bí ìdàgbàsókè èso ìmọ̀ẹ̀rọ. Ó sọ ọ́ di mímọ̀ pé láìsí ìmọ̀ẹ̀rọ, kò lè sí àyè fún ohun tí a lè pè ní ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé (Oghogho, 2008: 214). Bákan náà ni Ohiagu (2010: 113) gbà pé ìṣàmúlò ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ní ipa pàtàkì tó ń kó nínú àṣà àti ìṣe àwọn ènìyàn. Ó wá gbà pé bí ó ṣe wúlò fún ìlò ọmọ ènìyàn náà ló tún ní àwọn àléébù kan nítorí púpọ̀ nínú àwọn ènìyàn àwùjọ ló ń ṣe àmúlò rẹ̀ lọ́nà òdì. Johnson (2012: 12) ní tirẹ̀ rí i pé ìlò ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé mú àṣà ilẹ̀ adúláwọ̀ di ohun tó gbòòrò èyí tí kò ní jẹ́ kí àwọn àṣà náà lọ sí oko ìparun.

Dominick (2012: 94) gbà pé:

> Social media are media for interaction and relationship, largely informal and they are now popular means of communication and quite accessible. They are popular because they can be accessed with ease on a variety of platform – laptops, netbooks, smart phones, etc.
>
> Ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé jẹ́ ọ̀nà tó ní í ṣe pẹ̀lú ìfarakínra àti àjọṣepọ̀ tó gún régé, ó gbòòrò, àti pé wọ́n ti di ìlú mọ̀-ọ́n-ká nínú ètò ìbánisọ̀rọ̀ èyí tó jẹ́ àtẹ́wọ́gbà káàkiri. Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ yìí gbajúmọ̀ nítorí a lè ṣàmúlò wọn pẹ̀lú ìrọ̀rùn ní onírúurú ọ̀nà bí i ẹ̀rọ

kọ̀ǹpútà àgbélétan, ìwé àkàgbọ́ lórí ẹ̀rọ, ẹ̀rọ ìpè ìlewọ́, abbl.

Síwájú sí, Duarte (2009: 19) sọ pé:

> Social medial is a form of media created by people who posted information be the picture, articles, videos, etc.
>
> Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé jẹ́ abala tí àwọn ènìyàn fi ọgbọ́n ìmọ̀ ẹ̀rọ ṣe àgbékalẹ̀ láti ṣe ìtànkálẹ̀ ìròyìn bóyá nílànà àwòrán, átíkù, fídíò, abbl.

Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ yìí kan náà ni ó tún jẹ́ okùnfà ìsopọ̀ láàrin àwùjọ kan sí àwùjọ mìíràn. Onírúurú ìwúlò ló ṣodo sínú ilànà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé yìí, lára ìwúlò náà ní ṣíṣí àwùjọ níyè nípa ohun tó ṣókùnkùn síni. Síṣe ìpolongo ara-ẹni, iṣẹ́ ẹni àti ìpolówó ọjà, láti fi pàrokò ọ̀rọ̀, sísọ ìtàn tí àwọn ènìyàn kò mọ̀ nípa rẹ̀ rí, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

A lè rí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé yìí bí ìgbáṣà làrugẹ èyí tí yóò dènà oko ìparun fún àwọn nǹkan tiwa-n-tiwa. Bákan náà ló ń ṣèrànwọ́ láti jẹ́ kí àwọn ènìyàn tó wá láti inú àṣà mìíràn ní ìmọ̀ kíkún nípa àṣà tí ó jẹ́ ti àwọn ẹ̀yà mìíràn. Nípa èyí, ìfiwéra àti ìfagagbága yóò lè wáyé. Yàtọ̀ fún àwọn ẹ̀yà mìíràn, àwọn tó jẹ ọmọ Yorùbá tí kò ní ìmọ̀ kankan nípa ohun àwùjọ yóò ní àǹfààní láti mọ ohun tó ń ṣẹlẹ̀ nínú àṣà wọn. A tún lè rí ọ̀nà yìí gẹ́gẹ́ bí oríkì tí olùsọ ń gbà fi ohun tí wọn ń fẹ́ kí ènìyàn mọ̀ nípa àwọn ránṣẹ́ sí olùgbọ́.

**Ipa ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé lórí ìpàtẹ òògùn ìbílẹ̀**

Òògùn ìbílẹ̀ ní a lè rí bí ọ̀nà àbáyọ kúrò lọ́wọ́ àìsàn nípasẹ̀ ìlò tewé-tegbò. Ìlànà yìí jẹ́ mọ́ yẹ̀-ń-wò lọ́dọ̀ àwọn babaláwo àti àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ láti yanjú ìṣòro àìsàn tó ń pá ẹ̀dá láyà.

Dọ̀pámù (1979: 72) sọ pé

> Medicine is an act of using the available resources of nature to prevent or cure diseases. In other words, it is an art aimed at restoring and preserving health by means of medicament.
>
> Òògùn jẹ́ iṣẹ́, ọ̀nà tí à ń gbà ṣe àmúlò ohun-èlò tí adẹ́dàá fi sí àrọ́wọ́tó ọmọ ènìyàn láti dènà tàbí ṣe ìwòsàn onírúurú àìsàn. Ní ọ̀nà mìíràn, ó tún jẹ́ ìlò òògùn láti ṣe ìdápadà àti ìtọ́jú ìlera nínú àgọ́ ara.

Oríṣìíríṣìí òògùn ìbílẹ̀ ló wà fún ìtọ́jú àti ìdènà àìsàn. Àwọn àìsàn bí i àìsàn ẹran ara, ojú, eyín, àrùn ọpọlọ, rọmọlọ́wọ́-rọmọlẹ́sẹ̀, eegun títò, ìtọ́jú aláboyún àti ọmọ wẹ́wẹ́, abẹ dídá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àpẹẹrẹ iṣẹ́ abẹ tìbílẹ̀ ni ọta ìbọn yíyọ, oyún ìju, abẹ dídá, eegun títò, abbl. A lè rí àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí gẹ́gẹ́ bí olùtọ́jú àìsàn yòówù tó ń bá àwọn ènìyàn àwùjọ fínra. Oríṣìíríṣìí orúkọ ni wọ́n máa ń pe àwọn olóògùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí. Wọ́n lè pè wọ́n ní oníṣègùn, elégbòogi tàbí babaláwo, àmọ́ oko kì í jẹ́ ti baba tọmọ kó má ní ààlà. Láàrin àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí, kálukú ló ni gbèdéke ohun tó lè ṣe. Iṣẹ́ ìṣègùn ẹlòmíràn jẹ mọ́ eegun títò (teegunteegun), ìtọ̀jú àìsàn àwọn èwe (eléwé ọmọ), ìtọ̀ ṣúgà, àìsàn ẹ̀jẹ̀ ríru, bákan náà ní a rí ẹni tó jẹ́ pé iṣẹ́ abẹ nílànà ìbílẹ̀ pọ́nńbélé ni iṣẹ́ rẹ̀ jẹ mọ́. Yàtọ̀ sí èyí, ẹlòmíràn nínú wọ́n lè sọ wí pé gbogbonṣe ni tòun. Bí àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀

ṣe wà náà la rí àwọn tí wọ́n jẹ́ onímọ̀ tewé-tegbò (pharmacist) tìbílẹ̀ tí a mọ̀ sí léku-lẹ́ja.

Ipa pàtàkì tí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ń kó nínú ìpàtẹ òògùn ìbílẹ̀ ni láti bá àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí polongo ọjà wọn tí wọ́n fẹ́ tà fáráyé àti láti rí i dájú pé iṣẹ́ tí wọ́n fẹ́ jẹ́ fún olùgbọ́ wọn fẹsẹ̀ rinlẹ̀ dáradára. Nípasẹ̀ ìfẹsẹ̀rinlẹ̀ ìpolówó lóòrèkóòrè ni yóò ṣe okùnfà ìdásí olùgbọ́. Ọ̀nà ìpolówó yìí gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí yóò fanimọ́ra tàbí pàrọwà fún àwọn olùgbọ́ láti rà nínú ohun tí wọn ń tà. Yàtọ̀ sí èyí, wọn máa ń ṣe ìpolongo ọjà wọn pẹ̀lú oríkì, àwòrán àti onírúurú àpèjúwé yálà ara wọn àti ọjà tí wọ́n fẹ́ tà.

Adébàjò (1986: 55) gbà pé oríkì ni ó ń júwe ìwà, iṣẹ́ àrà olóríkì, èyí tó ń mú àwọn òǹrajà àti òǹkàwé ìròyìn mọ nǹkan púpọ̀ nípa ọjà tí wọ́n ń polówó rẹ̀. Yàtọ̀ sí èyí, bí wọ́n ti ń ṣe ìpolówó ọjà nínú ìwé ìròyìn bẹ́ẹ̀ náà ni wọn ń ṣe é nínú àwọn ẹ̀rọ ìgbàlódé, èyí sì jẹ́ kí ìkéde wọ́n rìn káàkiri àgbáyé.

## Ìpolongo Òògùn Ìbílẹ̀ Yorùbá

Àwọn òǹtajà gbà pé ìpolówó ọjà ni àgúnmu òwò. Ìpolówó ọjà jẹ́ ọ̀nà tí a lè gbà láti ṣe ìròyìn nípa ọjà tí a fẹ́ tà àti láti pàrọwà lórísìírísìí nípa bí ọjà yóò ṣe tà tí àwọn olùgbọ́ yóò sì máa ra ọjà náà wìtìwìtì. Adébàjò (1986: 55) pín ìpolówó ọjà sí ọ̀nà méjì. Àkọ́kọ́ ni ìpolówó ọjà pẹ̀lú àwòrán nígbà tí èkejì jẹ́ ìpolówó ọjà pẹ̀lú oríkì ọjà náà. A lè rí ìpolówó ọjà gẹ́gẹ́ bí ètò tí a ti là kalẹ̀ láti mú kí ọjà tí a fẹ́ tà fún òǹrajà yá kánkán ní ète láti lè rí èrè tiwa jẹ. Ọ̀nà méjì ni a fẹ́ gbà láti wo ọ̀nà ìtàjà òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá. Ọ̀nà àkọ́kọ́ ní ọ̀nà ìpolówó òògùn ní ayé àtijọ́, ìkejì sì ni ìpolówó òògùn ní ayé òde-òní.

Ọmọ́paríọlá (1985: 20) gbà pé ìpolówó ọjà orí rédíò àti tẹlifísàn jẹ́ nǹkan tí ọ̀làjú kó dé àwùjọ wa. Ó sọ ọ́ di mímọ̀ pé ọ̀nà ọ̀tọ̀ ni wọ́n ń gbà láti ṣe ìpolówó ọjà tiwọn èyí tó mú kí ó wú àwọn ènìyàn lórí láti gbọ́. Ó jẹ́ kí á mọ̀ pé ìpolówó yìí le è wáyé nílànà ohùn ìsàré, orin tàbí ìsọ̀rọ̀kéwì. Ó jẹ́ kí á mọ̀ pé ewì ìkiri kì í gùn èyí tó mú kí ìyàtọ̀ wà láàrin ìpolówó ọjà lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé.

## Ìpolówó Òògùn Ìbílẹ̀ ní ayé àtijọ́

Kí ìṣàmúlò ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé tó wọ àwùjọ Yorùbá ni àwọn ènìyàn tí wọ́n yan iṣẹ́ ìṣègùn láàyò ti ní ọ̀nà ìpolówó ọjà tiwọn láti ṣe ìtọ́jú àwọn ènìyàn wọn lọ́nà tí kó rújú. Ní ayé àtijọ́ kò sí rédíò, tẹlifíṣàn, ìwé ìròyìn tàbí ọkọ̀ tó lè gbé wọn lọ sí ibi tí wọn ti lè polówó ọjà wọn ju kí wọn di òògùn wọn sínú àpótí onígi, kí wọn sì gbé e lórí máa kiri káàkiri. Ní àkókò tí a wí yìí, ọjọ́ ọjà kọ̀ọ̀kan, yálà ó sún mọ́ ibùgbé wọn tàbí ó jìnnà sí i, ni wọn yóò máa ṣọ́ láti gbé òògùn wọn lọ. Ọjọ́ ọjà yìí lè jẹ́ ọjọ́ márùn-ún márùn-ún, bí ó sì ti wù kó jìnnà tó, àwọn oníṣègùn yìí yóò forí lé ibẹ̀ nítorí ọjà tí wọ́n fẹ́ tà. Àwọn tí wọn ń ta òògùn yìí ní ibi tí wọn ń dé sí, wọ́n sì mọ̀ wọ́n dáradára. Bẹ́ẹ̀ ni wọ́n sì mọ abúlé tí wọn ti ń wá polówó òògùn fún wọn. Ọjà kan ni wọn máa ń gbà dé ọjà mìíràn èyí tó mú wọn gbajúmọ̀ tí ojú sì tó wọn dáradára. Wọ́n máa ń lóòótọ́ pẹ̀lú ọjà tí wọn ń tà nítorí tí wọn bá parọ́, ọwọ́ yóò tẹ̀ wọ́n níbòmíràn tí wọn bá ti lọ tajà. Fúnra àwọn olóògùn wọ̀nyí ni wọ́n ń tajà wọn, kò sí alágbàtà bí ti òde-òní bẹ́ẹ̀ ni àyíká wọn tí wọn ti ń tajà ni wọn yóò ti gbajúmọ̀. Ohun tó ṣe okùnfà èyí kò ju wí pé ọgbọ́n ìgbóhùn sáfẹ́fẹ́ bí i tòde-òní

kò sí lásìkò tí à ń sọ̀rọ̀ rẹ̀ yìí. Fún ìdí pàtàkì yìí, kò sí àǹfààní láti mọ̀ wọ́n pẹ̀lú iṣẹ́ wọn káàkiri ju agbègbè wọn nìkan.

Ìlànà tí wọn tún máa ń lò nígbà mìíràn jẹ mọ́ ìtọ́wò ọjà wọn, àwọn tó lò ó tí wọn rí bí ó ti ṣiṣẹ́ ni wọn yóò máa sọ fúnra wọn. Èyí sì máa ń mu òògùn wọn tà wìtìwìtì, kò sí irọ́ pípa ní àkókò yìí. Òògùn tí wọn bá mọ̀ láti tọ́jú aláìsàn ni wọn yóò polówó rẹ̀.

Ìlànà ìtajà wọn lè mú ijó jíjó, ìlù lílù àti onírúurú ìpohùn dídùn tí yóò fa àwọn oníbàárà wọn mọ́ra lọ́wọ́. Àwọn wọ̀nyí kò nílò kí wọ́n pólongo ara wọn, iṣẹ́ ọwọ́ wọn ló máa ń ṣe àfihàn wọn. Ìpolówó ọjà ayé àtijọ́ yìí máa ń wáyé ní àwùjọ tí kò jìnnà síra wọn rárá. Láàrin ìlú tàbí láàrin ìletò kan sí èkejì ni èyí ti wúlò. Láti lọ polówó ọjà láti ibìkan dé ibìkan máa ń gba òógùn àti àkókò. Èyí kò rí bẹ́ẹ̀ lásìkò ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé yìí nitorí pé àǹfààní wà fún olùgbọ́ àti olùsọ láti wá ara wọn kàn níbikíbi tí wọ́n bá wà pẹ̀lú ìlànà yìí. Èyí fi hàn gbangba pé ọ̀làjú òyìnbó àti àṣà mọ̀-ọ́n-kọ-mọ̀-ọ́n-kà ti mú àyípadà bá ètò ìpolówó ọjà láwùjọ Yorùbá. Èyí ló sì ṣe okùnfà bí ètò ọrọ̀-ajé ṣe gbèrú sí i láàrin àwùjọ.

## Ìpolówó Òògùn Ìbílẹ̀ Yorùbá lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé

Onírúurú ọ̀nà ni àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ Yorùbá ń gbà ṣe ìpolówó ọjà wọn lóde-òní. Lára ọ̀nà tí wọn ń gbà polówó ara àti òògùn wọn ni gbígbé ara wọn sórí afẹ́fẹ́ yálà rédíò, tẹlifísàn tàbí ìwé ìròyìn, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọ̀pọ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ rédíò àti tẹlifíṣàn tó wà ní ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan bí Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun; Orísun F.M. (89.5Mhz) Ilé-Ifẹ̀; Gold F.M 95.5 Mhz) Iléṣà; Oòduà 90.9 F.M. Ilé-Ifẹ̀; OSBC Radio 104.5 F.M., Ilé Àwíyé, Ìbòkun Road; Ajílété F.M.

(92/Mhz) Ògbómọ̀ṣọ́, Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́; Splash F.M. (105.5 Mhz), Ìlọrin, Ìpínlẹ̀ Kwara; Sweet F.M. 107.1 Abẹ́òkúta; S.M.A. F.M. 104.7 Ìjẹ̀bú-òde; N.T.A. Ìjẹ̀bú-òde, Ìpínlẹ̀ Ògùn; LTV Lagos; NTA Àkúrẹ́, Ìpínlẹ̀ Oǹdó; àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ló máa ń bá àwọn oníṣègùn wọ̀nyí polówó ọjà wọn.

Iṣẹ́ tí àwọn ilé-iṣẹ́ agbóhùn sáfẹ́fẹ́ wọ̀nyí ń ṣe ni láti pọ́n iṣẹ́ àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí lọ́nà tí yóò gbà jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà lọ́dọ̀ òǹrajà. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí náà máa ń pọ́n ara wọn nípa lílo ìnagijẹ bí i: "Ọkọ Olóyún", "Ọmọ ìyá aláró", "Ọmọ ìyá àjẹ́", "Ọ̀pábìjà bàbá ń Gánà", "A-mú-bí-i-kánún", "Ewé-gbogbo-kìkì-òògùn", "Bàbá onífitílà", "Bàbá olójú-fitílà-mẹ́rìndínlógún", "Àdìtú bàbá èwe", "Olómitútù", "Dà-bí-àrà", "Òròkí Herbal Mixture", "Akérékorò", "Ọlọ́mọ yọyọ", "Lẹ́ṣẹ̀kẹṣẹ̀", "Ìdẹ̀ra dé", "Ẹ̀rọ̀ Àríkẹ́", "Afewé-ṣọlá Ìgbóminà baba ìdákọ̀lè", "Aládòó ọ̀rọ̀ jìngbìnnì oògùn", "Bàbá alágbo àdúrà alákèrègbè ìyanu", "Ẹ̀gbẹ̀jí awo ilé Ògbómọ̀ṣọ́", "Ìyá àbíyè" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Èyí máa ń wáyé láti jẹ́ kí olùgbọ́ wọn mọ bí agbára wọn ti tó nípa òògùn tí wọ́n ń ṣe. Ìnagijẹ tí wọ́n ń fún ara wọn jẹ́ orúkọ àpèjẹ́ yàlà àpè-mọ́ra-ẹni tàbí àdájẹ́ wọn, wọn ń fún ara wọn ní àwọn ìnagijẹ wọ̀nyí láti ṣe àfihàn iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe, òògùn tí kálukú wọn lè ṣe, ipò wọn, ìhùwàsí àti ìṣe, ibi tí agbára wọn dé dúró nínú iṣẹ ìṣègùn àti bí wọn ṣe gbójú, gbónu, gbóyà nídìí iṣẹ́ ìṣègùn wọn. Bákan náà ni èdè àmúlò fún ìpolongo òògùn wọn kò gbẹ́yìn. Bí àpẹẹrẹ ìpolówó òògùn Bàbá Àgbọmọlà lórí tẹlifíṣàn NTA Mòkúrò, Ilé-Ifẹ̀,

1. Èmi afewé gbọmọlà nígbà ìpọ́njú
Afegbò túni sílẹ̀ nígbà ìṣòro
Ìsọ̀yè a-jẹ́-bí-idán àti ẹ̀rọ̀ ìgbóná
La á fi ṣe ìtúsílẹ̀

Àtewé àtegbò
T'Olódùmarè ọbaa mi ọ̀fẹ́ ni

Ìpèdè rẹ̀ fi hàn pé, ó máa ń fi ewé àti egbòogi ṣe ìtúsílẹ̀ àwọn ènìyàn nínú àìsàn ìgbóná àti ẹni tí ó bá ń gbàgbé nǹkan.

Ìwádìí jẹ́ kí a mọ̀ pé ẹni tí àìsàn ìgbóná bá ń dà láàmù yóò máa ṣe wọ́nranwọ̀nran, ara olúwarẹ̀ yóò gbóná janjan, irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ kò ní rí oorun sùn bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀fọ́rí kò ní jẹ́ kí ẹni náà gbádùn. Ẹ̀rọ̀ ìgbóná náà ni: imí esú, epo pupa, ewé imí esú rẹ́rìn-ín-kò-mí àti osùn. Ọ̀nà méjì ni a lè gbà fi pèṣè oògùn yìí. Àkọ́kọ́ ni kí a ra ewé imi eṣú tí yóò fi yọ omi jáde, a ó fi sínú epo pupa, a ó máa fún ẹni tí àìsàn yìí kọlù mu. Ọ̀nà kejì ni kí a ra ewé imi rẹ́rìn-ín-kò-mí kí ó yọ omi jáde, a lè po omi rẹ̀ papọ̀ mọ́ epo pupa tàbí ọṣẹ dúdú kí a máa fún aláìsàn mu. A sì tún lè fi omi ewé rẹ́rìn-ín-kò-mí yìí sínú kẹrosínìnnì kí a máa fi pa ìta ara ẹni tí ìgbóná yìí ń dà láàmú. Bí ẹni náà bá mu ún tí ó sì fi para, tí kò bá róorun sùn tẹ́lẹ̀, fọnfọn ni yóò sùn lọ. Èròjà oògùn ìsọ̀yè nìwọ̀nyí: ewé ṣawere-pèpè, ewé amúnimúyè, ewé rinrin mẹ́sàn-án, àti ataare ẹyọ kan. A ó sá wọn gbẹ dáradára, a ó wá lọ gbogbo rẹ̀ papọ̀, a ó fi sín gbẹ́rẹ́ yíká ìdodo ẹni tí ó ń gbàgbé nǹkan.

Nínú ìpolówó Bàbá Ewé gbogbo-kìkì-òògùn lórí rédíò OSBC 104.5 FM, Ilé-Àwíyé Ọ̀ṣogbo

2. Èmi ewédọgbọ́n
Ọmọ Amóṣùn
Tó ń ṣe ìtọ́jú ara ẹ̀dá
Òògùn àyà jíjá ń bẹ lọ́wọ́ ọmọ bíbí Amósùn
Ibùsọ̀ mi àti búkà mi
Wà ní ojúlé kejì
Ìgbọ̀nà ni Ọ̀ṣogbo
Ẹ wá bá mi rà ní wìtìwìtì

Àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé a máa ṣe àmúlò yìí láti polongo tàbí sọ fún àwọn ènìyàn àwùjọ nípa ọjà wọn àti ibùdó tí wọ́n wà kí ó lè rọrùn fún àwọn olùgbọ́ wọn láti rí wọn. Òògùn àyà jíjá ni oníṣègùn yìí yàn láàyò. Ẹni tí àìsàn yìí bá ń ṣe gẹ́gẹ́ bí ìwádìí ti fi hàn ni pé àyà aláìsàn náà yóò máa lù kì kì kì léraléra. Àwọn èròjà òògùn tí wọn yóò lò ni orí ìjàpá pẹ̀lú odidi ataare. A ó jó o papọ̀ nínú agbada. A ó máa fi fọ́ ẹ̀kọ tútú mu.

Àpẹẹrẹ nínú ìpèdè Bàbá Ọlọ́mọyọyọ lórí Ajílété F.M. (92/Mhz) Ògbómọ̀ṣọ́ lọ báyìí pé:

3. A kì í gbẹ̀bí ewúrẹ́
Ẹnìkan kì í gbẹ̀bí àgùntàn
Ọmọ yọyọ lẹ́yìn adìẹ
Ewé kì í bọ́ lára igi
Kó nigi lára
Wẹ́rẹ́ la áà gbọ́

Ìpèdè yìí fi hàn pé tí oyún bá ti dúró sára obìnrin tí àsìkò ìbímọ sì ń súnmọ́ pẹ̀lú àtìlẹyìn Ọlọ́run àti tirẹ̀ wẹ́rẹ́ laboyún yóò sọ̀ kalẹ̀. Ṣùkù àgbàdo àti odidi ataare kan náà wúlò púpọ̀ fún ìtọ́jú aláboyún. A ó jó méjèèjì papọ̀. Tí a bá ti ṣe èyí tán, a ó fi sín gbẹ́rẹ́ fún aboyún náà, yóò sì fi èyí tó kù fọ́kọ mu.

Àpẹẹrẹ nínú ìpolówó Akéré-korò ti orí rédíò Oòduà 90.9 F.M., Ilé-Ifẹ̀ sọ pé:

4. Bíntín lata, tí fi ń ṣọkọ ojú
Ara títa, nárun
Òògùn ti yóò woni sàn
Lè má ju bíntín lọ.

Àìsàn yìí jẹ́ èyí tó ń mú ara títa wáyé, tí ara yóò sì máa já ènìyàn jẹ ní oríkèèríkèé ara nígbà tí nárun máa ń mú ara híhọ lọ́wọ́.

Èròjà òògùn ara títa ni ata ìjọ̀sì àti yèrèpè. A ó jó o papọ̀ nínú oko. Bí a bá jó o tán, a ó dà á sínú epo pupa, wọn yóò máa fi pa ara. Èròjà òògùn nárun ni: ìyèré, ẹ̀rú alamọ, ọmọ inú ataare mẹ́sàn-án, ewé ètìpo-ọlà. Gígún ni a ó gun pọ̀ tí a ó máa fi mu ẹ̀kọ gbígbóná.

Nínú ìpèdè rẹ̀, ó jẹ́ kí a mọ̀ pé lọ́pọ̀ ìgbà àwọn ènìyàn máa ń fojú di nǹkan tí kò pọ̀ nítorí pé ó kéré. Tàbí kí a fojú di òògùn tí wọn kò gbówó lé. Nínú ìpolówó òògùn rẹ̀, ó fi ata ṣe àpèjúwe pé bí ata ṣe kéré tó, kó ṣe é fojú di. Ó fi yé wa pé, òògùn tí yóò mú àlàáfíà bá àgọ́ ara lè má jú bíntín lọ tí ìṣọwọ́ ṣíṣẹ́ rẹ̀ yóò sì ya ènìyàn lẹ́nu.

Ìpolówó oníṣègun Bàbá Lẹ́sẹ̀kẹṣẹ̀ lórí Rédíò Sweet F.M. 107.1 Abẹ́òkúta lọ báyìí pé:

5. Lẹ́ṣẹ̀kẹ́ṣẹ̀ orí fífọ́ dohun ìgbàgbé
Lẹ́ṣẹ̀kẹ́ṣẹ̀ àrùn àwọ́ká dohun ìpamọ́lẹ̀
Gbé lẹ́ṣẹ̀kẹ́ṣẹ̀ lura kó o sara gírí

Ìpèdè inú ìpolówó ọjà yìí ń fi yé wa pé tí enyan bá wà nínú ìnira tí òògùn Lẹ́sẹ̀kẹ́ṣẹ̀ sì ń bẹ nítòsí, bí wọ́n bá ti gbé e lúra, lọ́gán ni ara níni yóò dohun ìgbàgbé. Ìpolówó òògùn rẹ̀ dá lé orí fífọ́ àti àwọ́ká.

Nínú ìwádìí tí a ṣe, ibà máa ń mú orí fífọ́, inú rírun, òtútù àti ara ríro dání nígbà mìíràn. Tí nǹkan báyìí bá ń ṣẹlẹ̀, wọn á gbìyànjú láti tọ́jú olúwarẹ̀ pẹ̀lú òògùn ibà. Wọ́n sì tún gbà pé àwọ́ká máa ń jẹ jáde lásìkò òtútù ni gbogbo oríkèèríkèé ara èyí tó le dá ènìyàn gúnlẹ̀. Àwọn èròjà àwọ́ká ni, mùdùnmúdùn ẹṣẹ̀ màlúù, ẹyin adìyẹ ìbílẹ̀ kan, àlùbọ́ṣà funfun kan, káńfọ̀ àti káfúrà. A ó lọ gbogbo rẹ̀ papọ̀, a ó sì pò wọ́n pọ̀ mọ́ òrí gidi. A ó máa fi wọ́ ara láti òkè lọ sí ìsàlẹ̀.

Ìwádìí kejì fi hàn pé orísìírísìí ibà ló wà, èyí tó lè fa kí orí máa fọ́ ènìyàn. Lára irúfẹ́ ibà náà ni ibà pọ́njú-pọ́ntọ̀ tí a mọ̀ sí *yellow fever*. Àwọn èròjà rẹ̀ ni; ihá ẹ̀yìn àgbọn, omiídùn, ọsàn ganingánín, ọsàn gíréèpù àti ọ̀pẹ̀ òyìnbó dúdú. Ihá ẹ̀yìn àgbọn la ó fi tẹ́lẹ̀ nínú orù, a ó wá kó gbogbo èròjà tó kù le lórí, a ó sì da omiídùn (omi tí a yọ́ lórí ògì) le lórí, a ó sè é títí tí yóò fi jinná. Ẹni tí ibà yìí ń ṣe yóò máa yọ́ ọ mu díẹ̀ díẹ̀ láàárọ̀, ọ̀sán àti alẹ́.

Ìpolówó òògùn Ọ̀pádìjà Bàbá-ń-Gánà ní Splash F.M. (105.5 Mhz) Ìlọrin lọ báyìí pé:

6. Ewé dọgbọ́n, egbò dère
Ohun tó ń já ọ láyà kúlúkú
Máa gbé e bọ̀ nílù ú Ìlọrin
Ìwọ obìnrin tí nǹkan oṣù rẹ ń ṣe ṣégeṣège
Máa bọ̀ wá gba ìgbàlà
A ó fi ewé àti egbò wò ọ́ sàn
Ní owó tí kò gunpá

Ó fi ye wa nínú ìpolówó rẹ̀ pé Ọlọ́run fi ewé àti egbò dá òun lọ́lá láti ṣe ìwòsàn tó bá jẹ mọ́ ọ̀rọ̀ nípa obìnrin. Inú obìnrin tí àìsàn yìí bá ń dà láàmú yóò máa gbóná, ẹ̀jẹ̀ tó bá ń jáde nígbà tó bá ń ṣe nǹkan oṣù yóò dúdú, bẹ́ẹ̀ ni kò ní wá lásìkò tó yẹ gẹ́gẹ́ bí ìwádìí tí ṣàfihàn rẹ̀. Èròjà òògùn àìsàn yìí ni: ìdàn-ǹ-dán, osùn, kárańdáfí àti kánún bílálà. A ó lọ gbogbo rẹ̀ papọ̀, aláìsàn yóò máa fi mú ẹ̀kọ gbígbóná láàárọ̀ àti lálẹ́.

Ìpolówó òògùn mìíràn ni *Gangaria de flush* nínú tẹlifísàn NTA Àkúrẹ́ tó lọ báyìí pé:

7. *Gangaria* tún ti dé
*Herbal mixture*
Òògùn ìbílẹ̀ yìí le kú o
Ó múná dóko

Iṣẹ́ tí òògùn *Gangaríà de Flush* máa ń ṣe ni inú fífọ̀. Ó wà fún ẹni tí kò rí ìgbẹ́ yà déédé tàbí tí inú rẹ̀ ń kùn tó sì ń gbóná. Àwọn èròjà bí ìwádìí ti fi hàn ni ewé tanutanu (mint leave), ọsàn gan-in-gán-ín (lemon), ọsàn wẹ́wẹ́ (lime), àti atalẹ̀ (ginger). Wọn yóò rẹ gbogbo èròjà wọ̀nyí sínú omi fún odidi ọjọ́ kan. Lẹ́yìn tí ó bá toró dáradára, á ó máa mu gàásì kọ̀ọ̀kan kí á tó jẹun láàárọ̀. A sì tún lè máa mu ún bí omi lẹ́yìn oúnjẹ. Ìpolówó yìí fi hàn pé òògùn rẹ̀ a-jẹ́-bí-idán ni

Ìpolówó Ọmọ ìyá Aláró ní Gold F.M. 95.5 Iléṣà sọ pé:

8. Kékeré la bérin sínú igbó
Orí kíkú ò lè ṣàǹfààní fọ́mọ aráyé
Òògùn òsúkè (èsúkè)
Jẹ̀díjẹ̀dí ọkọ akọ ń bẹ lọ́wọ́ wa
Tiwa yàtọ̀ sí ti afọ̀sánwọ̀

Òògùn fún ẹni tí jẹ̀díjẹ̀dí ń bá fínra àti èsúkè síṣe ni onísègùn Agbọmọlà ń bá wí. Àwọn èròjà fún òògùn èsúkè ni: awùsá tútù tí wọn kò tí ì ṣè, a ó fún ẹni tó ń ṣe èsúkè pé kí ó jẹ ẹ́, kí ó sì gbé omi rẹ̀ mì. Èsúkè yóò lọ. Èròjà òògùn jẹ̀dijẹ̀dí ni: òdòdó òsùnwọ̀n tó pọ̀ díẹ̀, a ó sa a tí yóò gbẹ, a ó fi aálọ̀mù díẹ̀ sí i, a ó máa fi fọ́ ẹ̀kọ mu. Ìpolówó rẹ̀ fi hàn pé àwọn òbí òun jẹ́ jáwé-jágbò ṣòògùn àwẹ̀dá ṣọmọ aráyé lóore, àti pé ìkápá òun ni ojúdá òògùn-a-jẹ́-bí-idán wà.

Ìpolówó Eroxil tútáosàn lórí rédíò SMA FM. 104. 7 Ìjẹ̀bú-òde sọ pé:

9. Kí ló mú ara ta pọ́n-ún-pọ́n-un?
*Eroxil* tútaosàn
Ṣebí òun ló mú mi ta pọ́n-ún-pọ́n-ún?

Ìpèdè yìí fi irú iṣẹ́ tí a ń lo òògùn yìí fún hàn gẹ́gẹ́ bí ohun ti ó máa ń mú ara yá kankan láìsí ìrẹ̀wẹ̀sì kankan.

Síwájú sí i, ìpolówó Bàbá olójú-fìtílà-mẹ́rìndínlógún nínú tẹlífísàn LTV, Lagos sọ pé:

10. Sínkún-sìnkùn-sínkún
Ó mú tọ̀ún sínkún
Ó mú tibí sínkún
Ìgbẹ́ eyín sínkún
Sínkún ló mu sínkún
Ara wíwú sínkún
Sínkún ló mú sínkún

Òògùn eyín ọmọdé àti ara wíwú ni oníṣègùn ìbílẹ̀ yìí ń polówó. Ọmọ tí ó bá ń ṣòjòjò eyín, ara rẹ̀ yóò gbóná janjan, yóò máa bì, àtijẹun yóò sì dọ̀ràn pẹ̀lú. Èròjà òògùn eyín gẹ́gẹ́ bí ìwádìí tí a ṣe ni ewé, èkùyá díẹ̀, orí ejò kékeré kan, a ó gún mọ́ ọṣẹ dúdú, a ó fi máa fọ orí ọmọ náà. Bí ara ènìyàn bá ń wu tí ó rí bòmùbòmù, èròjà òògùn fún ìwòsàn rẹ̀ ni: eegun ara ògiri, káfúrà kan, orí ọ̀jọ̀lá, a ó gún gbogbo rẹ̀ papọ̀, a ó sì pò ó mọ́ òríàmọ́, a ó sì máa fi pa gbogbo ara.

Nínú ìpolówó Eroxil tútaosàn (Eroxil 2002)" , "Gangaria de flush", àti "Herbal mixture", a kò ṣàìrí ìlò ọfọ̀ bí i "ẹnìkan kì í gbẹ̀bí ewúrẹ́, ewé kì í bọ́ lára igi kó nigi lára". Bákan náà ni ìlò òwe bí i "Bíntín lata, tí fi ń sọkọ ojú fara hàn". A kò tún ṣàìrí ọ̀nà ìtahùn síra pẹ̀lú ìsọhùndèèyàn bí i: "kékeré la bérin sínú igbó" èyí tí ó fi erin wé ara rẹ̀ pé láti kékeré lòun ti wà nínú iṣẹ́ ìṣègùn yìí, "tiwa yàtọ̀ sí ti afọ̀sánwọ̀", ìyẹn ni àwọn tó rí iṣẹ́ yìí lọ́sàn-án gangan tí wọ́n sì bẹ́ mọ́ ọn láìní ìmọ̀ nípa rẹ̀ tẹ́lẹ̀. A rí èyí bí ọ̀nà ìtahùnsíra.

Yàtọ̀ sí èyí, pẹ̀lú gbogbo ọ̀nà ìpolówó wọn pé wọn gbóná girigiri nínú iṣẹ́ yìí, wọn kò kóyán Olódùmarè kéré nípa sísọ pé:

Ìgbìyànjú ni tiwa
Ọ̀dọ̀ Ọlọ́run ni ìwòsàn pípé ti wá

Ìpèdè wọn fi hàn pé bí àwọn lóògùn bí àrọ̀nì, Ọlọ́run ni ìgbekẹ̀lé àti ọ̀gá àwọn nídìí ìṣègùn wọn.

Bí a bá wo onírúurú ọ̀nà ìpolówó òògùn ìbílẹ̀ lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé, àkíyèsí fi hàn gbangba pé wọ́n ń ṣe èyí láti dánnú mọ́ iṣẹ́ òògùn wọn kí ó lè jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà lọ́dọ̀ olùgbọ́. Oníkálukú ni yóò máa sọ bí òògùn rẹ̀ ṣe múná to. Bákan náà ni àwọn oníṣègùn yìí máa ń ṣe àmúlò bátànì tó jẹ mọ́ orúkọ, iṣẹ́ òògùn wọn, ibi tí wọn tí ń ṣe e, ibi tí òǹrajà ti lè rí i rà àti ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ wọn láti lè tọpasẹ̀ wọn.

Ọgbọ́n ìtajà mìíràn fún àwọn oníṣègùn yìí ni pípolongo ara wọn wí pé ọ̀fẹ́ ni ìwòsàn. Tí àwọn oníbàárà bá dé ọ̀dọ̀ wọn tán, wọ́n á sọ pé kí wọ́n lọ gba káàdì, kí wọ́n sì tún sanwó àyẹ̀wò. Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé yìí lá rí gẹ́gẹ́ bí ìbáṣepọ̀ olùsọ àti olùgbọ́ tí ó mú rírà àti títà dání gẹ́gẹ́ bí èrò Escarpit (1971).

Ohun mìíràn tó wọ ìlànà ìpolongo ìtajà wọn lórí afẹ́fẹ́ ni sísọ fún àwọn olùgbọ́ pé kí wọ́n wá bá àwọn ní gbàgede ibi ìpàtẹ wọn. Kálukú wọn ló sì ní ojúlé ibi ìtajà kọ̀ọ̀kan ni ibi ìtajà òògùn ìbílẹ̀ tí wọn dá sílẹ̀ láti dá àwọn oníbàárà wọn lóhùn. Yàtọ̀ fún ìpéjọpọ̀ wọn lójú kan náà níbi ìpàtẹ òògùn, wọ́n tún dá ẹgbẹ́ sílẹ̀ láàrin ara wọn láti máa ṣe ìjírọ̀rọ̀. Ìpolongo ara wọn yìí jẹ́ ọ̀nà tí wọ́n ń lò láti fi di gbajúmọ̀ kí wọ́n sì di ìlú-mọ̀-ọ́n-ká.

Àǹfààní tí wọ́n tún ní ni pé kò sí ibi tí wọn kì í ti gbọ́ ìpolówó òògùn wọn pẹ̀lú ọ̀nà ìbánísọ̀rọ̀ ìgbàlódé yìí. Àwọn tó wà káàkiri àgbáyé ló ní àǹfààní láti bá wọn dòwò pọ̀. Ìtànkálẹ̀

yìí jẹ́ kí a mọ̀ pé òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá tayọ àwùjọ Yorùbá nítorí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn tí kì í ṣe ọmọ Yorùbá ló ní àǹfààní láti gbọ́ ìpolówó òògùn wọn. Yàtọ̀ sí èyí, òògùn ẹ̀yà mìíràn tún ń jẹyọ nínú ọgbọ́n ìṣègùn ẹ̀yà Yorùbá. Àwọn oníṣègun mìíràn tí wọ́n jẹ́ ẹ̀yà Yorùbá lè gba òògùn lọ́wọ́ àwọn Tápà kí wọ́n sì máa lo òògùn náà nílẹ̀ Yorùbá. Àwọn Tápa náà lè gba òògùn lọ́wọ́ Yorùbá kí wọn máa fi ṣe ìtọ́jú àìsàn tó bá ṣiṣẹ́ fún lọ́dọ̀ wọn.

Wàyí o, bí ìpolówó òògùn lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé yìí tí gbé òògùn ìbílẹ̀ ẹ̀yà Yorùbá lárugẹ tó, àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ kan wà tó jẹ́ pé àtijẹ́ ló gbé wọn débẹ̀. Jìbìtì ni púpọ̀ nínú wọn ń lu àwọn ará ìlú, tí wọ́n bá ti ráyè gbá àwọn ènìyàn tán, ẹ kò tún ni fojú kàn wọ́n mọ́.

## Àǹfààní Ìpàtẹ Òògùn lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé

Ní ayé ọ̀làjú yìí, àwọn ènìyàn wa ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà pàápàá àwọn ẹ̀yà Yorùbá tó jẹ́ babaláwo tí ń gbé ara wọn lọ sí ilé ìgbóhùn sáfẹ́fẹ́ láti lọ polongo ara wọn àti iṣẹ́ wọn fáráyé. Wọn ń ṣe ìpolongo ara wọn nínú ìwè ìròyìn, rédíò, tẹlifísàn, àti onírúurú ọ̀nà mìíràn, láti jíṣẹ́ wọn fún àwọn ènìyàn káàkiri. Èyí ló ṣe okùnfà ìpàtẹ òògùn ọdọọdún tó máa ń wáyé ni orílẹ̀-èdè Nàìjíríà láti fi ṣí àwọn ènìyàn àwùjọ níyè, kí ó sì fún wọn nímọ̀ láti gba tewé-tegbò gẹ́gẹ́ bí òògùn a-jẹ́-bí-idán tí wọn lè lò fún ìtọ́jú ara wọn. Síwájú sí i, ẹni tí àìsàn ń ṣe gan-an yóò ní ànfààní láti ṣàlàyé nípa àìsàn tó ń yọ ọ lẹ́nu fún oníṣègùn. Lọ́wọ́lọ́wọ́ báyìí, àwọn ìwé ìròyìn kan, rédíò, tẹlifísàn, abbl. ní abala kan tí wọ́n yà sọ́tọ̀ fún ìpolówó ọjà fún àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ wọ̀nyí ní ẹ̀ẹ̀kan lọ́sẹ̀.

Wàyí ò, àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ Yorùbá tó nímọ̀ tewé-tegbò ń rọ́wọ́ mú, ipa wọn nínú àwùjọ kò sì ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn rárá. Yàtọ̀ sí èyí, kò sí òògùn ìbílẹ̀ Yorùbá tí kò sí ni àrọ́wọ́tó nítorí ewé àti egbò tí wọn yóò fi pèṣè rẹ̀ kò nira láti rí. Kò dàbí òògùn òyìnbó mìíràn tí wọn máa sọ wí pé òkè òkun nìkan la ti lè rí i rà. Agbára láti rí owó òògùn ìbílẹ̀ rà kò nira rárá, èyí tí ó jẹ́ kí ó yàtọ̀ síká máa wa dọ́là àti pọ́n-ùn kírí ká tó rí àwọn òògùn òyìnbó mìíràn rà fún ìtọ́jú àìsàn.

**Aburú tó rọ̀ mọ́ ìpàtẹ Òògùn lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé**

Bí a bá wo ọ̀nà ìkéde àti ìpolówó ọjà àwọn oníṣègùn wọ̀nyí lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé, àkíyèsí fi hàn pé kò sí ohun tó dára tí kò ní aburú tirẹ̀ nítorí pé tibi-tire la dálé ayé. Lóòótọ́ lá rí àwọn tí ó jẹ́ olóòótọ́ lára àwọn olùpàtẹ òògùn wọ̀nyí tí ewé àti egbò igi wọn sì ń jẹ́,

Irúfẹ́ àwọn oníṣègùn wọ̀nyí tún ṣe àfikún ìmọ̀ nípa wíwá ìmọ̀ kún ìmọ̀ nílànà ìṣègùn òyìnbó láti ní àfojúsùn tó pegedé lórí ọ̀nà ìgbéjádé òògùn tí wọ́n fẹ́ ṣe jáde fún ìlò ọmọnìyàn àti bí lílo rẹ̀ yóò ti rí lọ́nà tí kò ní fi mú ìpalára lọ́wọ́ fún àwọn oníbàárà wọn. Bákan náà la rí àwọn oníṣègùn kan tí kò bìkítà rárá nípa irúfẹ́ òdiwọ̀n òògùn tí aláìsàn lè lò, èyí tó lè ṣe okùnfà onírúurú ìpalára fún àwọn aláìsàn. A ti rí oníṣègùn tó polówó kí nǹkan ọmọkùnrin ó le dáradára tí àwọn oníbàárà sì rà á tí wọn gbé e lura láiní ìwọ̀n. Àṣìlò òògùn báyìí ti sọ ẹlòmíràn di èrò ọ̀run nígbà tí nǹkan ọmọkùnrin rẹ̀ kò wálẹ̀ mọ̀ tí wọn kò sì rí ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro náà.

Lọ́pọ̀ ìgbà, àjọ tó ń gba ará ìlú sílẹ̀ tí a mọ̀ sí Nigeria Broadcasting Commission ni kì í jẹ́ kí àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀

wọ̀nyí ṣe ará ìlú ní ìjàm̀bá ju bó ṣe yẹ, amọ́ àjọ yìí ń gbìyànjú ni kì í ṣe gbogbo ohun tó ń ṣẹlẹ̀ lójú wọn tó.

Ìbá dára bí àwọn ìgbìmọ̀ wọ̀nyí bá lè tẹ̀ síwájú nínú akitiyan wọn láti dẹ́kun ìwà kòtọ́ tí irúfẹ́ àwọn oníṣègùn wọ̀nyí ń hù kí wọn má baà ta epo sí aṣọ àlà àwọn tí iṣẹ́ ìṣegùn wọn kún ojú ìwọ̀n.

## Àbá

Ọ̀nà àbáyọ lọ́wọ́ àwọn oníjìbìtì olóògùn ìbílẹ̀ yìí ni kí àwọn ìjọba gbé ìgbìmọ̀ tí yóò máa ṣe àmójútó wọn kalẹ̀. Iṣẹ́ tí àwọn ìgbìmọ̀ yìí yóò máa ṣe ni ṣíṣe àyẹ̀wò òògùn wọn, kí wọn tó gbé e sórí afẹ́fẹ́ láti dóòlà ẹ̀mí ará ìlú.

Ọ̀nà mìíràn ni kí àwọn oníṣègùn yìi máa pàdé lóòrèkóòrè láti máa jíròrò lórí iṣẹ́ ìṣègùn wọn àti láti máa gbà ara wọn ní ìmọ̀ràn nípa ohun tí ó bá rú èyíkéyìí nínú wọn lójú lórí iṣẹ́ yìí. Àwọn elétò-ìlera pàápàá gbọ́dọ̀ máa ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún wọn nípa bí wọn yóò ti máa ṣe ìmọ́tótó nídìí iṣẹ́ wọn àti bí òògùn tí wọ́n bá ń ṣe yóò ti ní òdiwọ̀n fún lílò. Yàtọ̀ sí èyí, ìfẹnukò gbọ́dọ̀ wáyé nípa bí ẹ̀dínwó yóò ṣe bá ọjà wọn nítorí púpọ̀ nínú wọn ló máa ń kọ owó iyebíye fún àwọn oníbààrà láti san. Ìgbàgbọ́ wa ni pé nǹkan tiwa-n-tiwa kò gbọdọ̀ gara ju bó ti yẹ lọ. Tí a bá ń ra òògùn òyìnbó ní owó gọbọi, tí ọ̀pọ̀ ènìyàn kò lè ní àǹfààní sí rírà rẹ̀, ó lẹ́tọ̀ọ́ láti rí òògùn ìbílẹ̀ tiwa rà láìsí ìnira rárá.

## Ìkádìí

Bí a ṣe rí àwọn oníṣègùn òyìnbó akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ láti ṣe ìtọ́jú onírúurú àìsan náà lá rí àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ tó dáńtọ́. Àmọ́ oko kì í jẹ́ tí baba-tọmọ kó máa ní ààlà, bí a ti rí àwọn tí ewé ń jẹ́ fún

nínú àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni a rí àwọn aláriwo lásán tí ó jẹ́ ọ̀nà láti lu ará ìlú ní jìbìtì ni wọ́n fi ń ṣe ìpolongo ara wọn lórí ẹ̀rọ ìgbàlódé yìí.

Fún ìdí pàtàkì yìí, bí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé yìí ṣe dára tó fún ìtànkálẹ̀ iṣẹ́ ìṣẹ̀nbáyé ìran Yorùbá bẹ́ẹ̀ náà ní a rí àléébù tó rọ̀ mọ́-ọn látàrí àwọn aláfẹnujẹ́ oníṣègùn ìbílẹ̀ awóyọjúràn lásán tí àwọn náà ń polongo ara wọn lórí afẹ́fẹ́.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adébàjọ̀, O. (1986). "Ewì Ìwòyí lórí Rédíò", Unpublished M.A. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Adekunle, Cythinia (2009). *Ìmọ̀ Sáyẹ́nsì àti Ẹ̀rọ Èdè Yorùbá.* Ìbàdàn: University Press Limited. o.i. 20-40.

Adésọ̀gán, E.K. (1998). "Scientific Rationale for Selected Nigeria Traditional Herbal Remedies. Proceedings of the 1st International Workshop on Herbal Medicine Products' Ibadan, o.i. 47-55.

Adéyẹmí, Lérè (2006). *Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ ní Èdè Yorùbá*. Ìjẹ̀bú-Òde: Shebiotimo Publications.

Agbájé, B. (1989). "Iṣẹ́ Ìṣègùn' nínú T.M. Ilésanmí (ol.) *Iṣẹ́ Ìsẹ̀nbáyé*. Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press.

Akpata, E.E. (1979). "Antibacterial Activity of Extract from Nigerian Chewing Sticks", Caries Res, o.i. 216-225.

Awólàlú J.O. àti Dọ̀pámú, A. (1979). *West African Traditional Religion.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press.

Churchill, Otieno (2009). "Mobile Media for Africa" nínú Francis Midlongwa OU Doing Digital media in Africa. Prospects, Promises and Problems. South Africa: Konrad Adonauer Stiftung Foundation.

Daurte, Dave (2009). How African Traditional Media can tap into new media" nínú Francis Mdlongwa (ol.) Doing Digital.

Dominick, J. (2012). *The Dynamics of Mass Communications.* Boston: McGraw Hill.

Dọ̀pámu, P.A. (1979) "Yorùbá Magic and Medicine and Relevance for today" nínú *Religion Journal of Nigerian Association for the study of Religion* vol 4.

Eégúnyọmí, (2007). "Aspect of the Yorùbá Scientific Knowledge of medicine Plants", *Yorùbá: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria,* 4(1).

Escarpit, R. (1971). *Sociology of Literature*. London: Frank Cass Co. Ltd.

Johnson, S.M.O. (2012). "A Critique of the New Media in Africa"(Internet)

Laurenson, D. àti Swingwood, A. 91971). *The Sociology of Literature*. London: Mac Gibbon and Kee.

Lowenthal, L. (1957). *Literature and the Image of Man*. Boston: Beacon Press.

Oghogho, U.O. (2008). "New Media Technology in the era of Gobalization of Broadcasting and this Democratic Process" nínú Omu, F.I. and Oboh, G. (eds). *Mass Media and Nigerian Democracy*. Ibadan: Stirling-Horden Publisher Nigeria Limited.

Ògúnbọ̀dẹdé, E. (1991). "Dental Care: The Role of Traditional Healers", *World Health Forum* 12(4), 443-444.

Ohiagu, O.P. (2010). "Influence of Information and Communciation Technologies on the Nigerian Society and culture" nínú Ekanyanwu, N. and Okeke, C. (eds.). *Indigenous Societies and Cultural Globalization in 21st Century*. Germany: VDM Verlang.

Olóròdé, O. (1985). "Aspect of Plant Naming and Classification among the Yorùbá". *ODU,* No. 27, 82-95.

Olúnládé, T.A. (2005). "Ìlò Lítíréṣọ̀ Alohùn Yorùbá láti ọdún 1859 dé 1960. Unpublished Ph.D. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Ọmọ́paríọlá, O. (1985). "Ìpolówó Ọjà Orí Rédíò ati Tẹlifísàn", Unpublished B.A. Disertation, University of Ifẹ́, Ilé-Ifẹ̀.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, J.A. (1997). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lo-èdè*. Òṣogbo: Tanimẹ́hìn-ọ̀la Press.

Ṣófowóra, E.A. (1970). A Study of Variations in Essential Oil of Cultivated Ocimum gratissimum, planta, medical, 17, 173.

## Àwọn Abẹ́nà-Ìmọ̀

| | **Orúkọ** | **Àdírẹ́ẹ̀sì** | **Iṣẹ́** | **Ọjọ́ orí** | **Ọjọ́ ìwádìí** |
|---|---|---|---|---|---|
| 1 | Amósùn Ifátókun | Ilé Towútowú Masifa, Ejigbo, Ìpílẹ̀ Ọ̀ṣun. | Babaláwo | 87 | 16/5/2016 |
| 2 | Ọjọ́awo Àlàdé | Ilé Onílárí Ejigbo, Ìpílẹ̀ Ọ̀ṣun | Babaláwo | 70 | 10/6/2016 |
| 3 | Ifágbémiga Ifálékè Òlómilágbalá | Iléṣà, Ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun. | Babaláwo | 63 | 20/6/2016 |
| 4 | Adélékè Mọ̀rúfù | Akéré-bí-ata Ìlọrin | Oníṣègùn ìbílẹ̀ | 65 | 10/7/2017 |
| 5 | Adéoyè Bàkàrè | Rédíò Orísun, Òkè Ìtaṣẹ̀ | Ọ̀gá Àgbà Àkaròyìn | 58 | 15/6/2016 |
| 6. | Adébáyọ̀ Samuel | N.T.A. Àkúrẹ́ | Akàròyìn | 53 | 21/6/2017 |
| 7. | Dakansinu Adétúnjí | Rédío Kwara, Ìlọrin | Olóòtú ètò | 64 | 6/5/2016 |
| 8. | Túndé | LTV Lagos | Akàròyìn | 28 | 14/6/2017 |

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| | Adéwálé | | | | |
| 9. | Múfúlìátù Sànúsí | Ilé-Lókòré, Ìfẹ́tẹ̀dó | Eléwé ọmọ | 45 | 20/8/2017 |